To The Chief Secretary to the Government


# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. VI. No. 264. SATURDAY, MARCH 3, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



8 MAR 1928



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

Victor White, Esq., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

Price: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ ***Fun Atọsi lailai ati titun.*** ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.


Adeniyi

Akin Adesipbun

"AWA O MA JO, AWA O MA YỌ, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akękęyęyę pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ęgbę, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

*Office* :—

No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

---

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKĘ Onişowo "Gbabiọgędę" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, ati lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilękun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simęnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ęrọ, ati Ọsan, ati Pakun ti Awo-ęja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ęja-şawa t'okun ati Ęja Abọmafọ, ni Şọbu rę ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işe Agbędę Iworo ati Fadaka.

**Owo Ọja rę fanimọra. Ę lọ ra tiyin nibę.**

---

**Are you a Mechanic ?—If so you must want Tools, now or soon.**

**Do you intend to put up a house ?—** Then you will require Builder's Hardware.

In either case you cannot do better than call at

***B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores***

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

---

***J. C. VAUGHAN***

Ti ile ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilękun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silę fun awọn Ọmọle ati awọn Gbęnagbęna: bi o fę da awo ni o, ęro-ija dida'wo ko ni ję ọ ni'ya lati ri nibę:

Alagbędę Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gba l'oşe fun ọ lati re yan irin-işę tirę nibę ba kanna.

Owo Ogbęni J. C. Vaughan ti di Owo Atanpako Ajanaku lọjọ to ti pę: bi Ogędę si ni Owo rę ngba kakiri ibikibi. Agbę ni ọ kai! bi o ri orişirişi Ọja ti o ri ra nibę ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbęnagbęna, iwọ Aranbata, iwọ Asenję iwọ Ageginigbo (Sawyer), Alagbędę Wura, iwọ Alagbędę Fadaka, iwọ Agbe re ba ori're tirę pade nibę.

**Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere nibę**

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RE

| | Eko | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/ |
| Oşu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/ |
| Oşu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/ |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

LADANI AYỌRUNBỌ, SỌNNU KEDE.

Irohin kan ni l'ọsẹ yi pe bi Imale kan ti npe'run Asuba ni kutukutuhai arọ *Monday* ni lọlọyi ni Mọşalaşi kan, bi o ti ke tantan pe "Alawu-aki-baru", gbirigidi bẹ ni o şubu lulẹ ti o si daku gbanrangandan; eyiti a nwi yi ti pẹ nigbati awọn enia ko si tun gbọ lilọ siwaju p pe na mọ, bẹ ni nwọn şi pĩ, rẹrẹ o di ibiti ọgbẹni na wa, ki nwọn ri, ki nwọn ri, bẹni nwọn ri pe o npọka iku; ẹniti o ni ogun aiperi nile mũ wa ati ogun etutu miran ti nwọn nfẹ si lẹnu, ẹniti o nfẹ oju nfẹ oju, ẹniti o si nfẹ eti nfẹ eti ọgbẹni na; nigbati o şe ti atẹgun fẹ si, bẹni o sọji o si bere kilo ti ri ti awọn enia fi rọgba yi on ka bẹ, nigbati nwọn si sọ idi abajọ na fun, nşe lo tauda lọ bi ilẹ bi ẹni; ara rẹ si ti gbọnnu ki o to kuro ni Mọşalaşi na.

OHUN WU MI KO WU Ẹ, A JẸUN LỌTỌTỌ

Gbogbo Enia Dudu Onigbagbọ lodẹ t'oni lo sọ pe ki işe ohun ti o dara lati gbeyawo ni akoko *Lent* ti a wa yi, sibẹ a ri awọn Coraa kan ti nwọn lọ gbeyawo ni Şọşi Aguda ninu ọsẹ to kọja ti mọto npe mọto ranşẹ: ka si tun ri, a ri awọn Oyinbo t'ọkọ-t'aya kan nigbakan, ti nwọn lọ gbeyawo ni ọjọ Satide. Eyi ti jẹ o, ẹnyin agbagba Onigbagbọ.

AJINDE ARA A MA JẸ.

Inu wa dun gidigidi nigbati a sọ fun wa wipe Oki Balogun Ilu ti bẹrẹsi lọ jọsin ni Mọşalaşi Jimọ lati ọjọ Jimọ ijẹsan lẹhin ailera ti o ti mbẹ fun u lati bi oşu melo sẹhin, eyiti gbogbo ẹnikẹni mọ pe ko fun ni aye lati lọ kirun Jimọ; k Oluwa fi ọran mọ bẹ o.

## AJỌ IGBIMỌ-AŞOFIN ATI INCOME TAX.

Lati ọwọ Kekere Awo.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Ajọ Igbimọ-Aşofin ti ilẹ Nigeria bẹrẹ lọjọ kejidinlogun oşu February to pari ni ijẹrin, nwọn si pari Ajọ na lọjọ *Monday* ọsẹ to kọ ja. Kosi ohun pataki kan julọ ti awọn ara ilu ni ireti lati mọ ninu Ajọ Igbimọ na, ti o ju oran owo "*Income Tax*" lọ, ki ilu le mọ inu odo ti nwọn ndọra si, gẹgẹbi o ti jẹ wipe ohun ni pataki ọran ẹdun ọkan fun ilu nisisiyi, lai mọ gẹgẹbi o ti lọ, aiya ilu kole balẹ, nwọn kole fi ẹdọ l'eri ororo, ọkan kole şun pẹtẹ pẹlu.

Şaşa enia ni kosi ninu kila-kilo fun ọran yi nigbati Ajọ Igbimọ kọ ni ireti pe kosi kansulu kan ti nwọn yio tun joko şe titi aseko bibẹrẹsi gbigba owo na gẹgẹbi ipinnu Ijọba yio fi to, eyiyi ni ọjọ kinni oşu April ti o ku bi ọjọ mejidinlọgbọn si.

Ki işe ọran owo-ori nikan ni awa ba lọrọ lati jihin fun nyin nipa Ajọ Igbimọ-Aşofin ti nwọn şe, a nşe kokari gbogbo ohun ti nwọn şe lọhun nisisiyi lati jihin eyiti a ko fẹ ki ọkan yapa ju si gbogbo ohun ti nwọn şe lọhun, ti o yẹ wipe ki a ri ni gasikiya, nipa eyi ni ko jẹki a le bẹrẹ loni lati şişẹ irohin ti Kansulu.

Bi ọran owo-Ajulọ ti olukuluku nreti lati gbọ opin rẹ, ba jẹ ohun ti nwọn tun fi pẹki rẹ ko pẹki l'ọtẹ yi a ki yio şe alai sọ gẹgẹbi o ba tilọ si, eyiti o ba si jẹ sawura nibẹ ti awa na le şe, a o jẹki gbogbo rẹ ye wa.

Şugbọn gẹgẹbi kokari irohin na ti a nşe lọwọ yi, ti a ba ri larin rẹ wipe, tọtun-tosi (Ijọba ati awọn Ọlọla Moore) ẹnikẹni ko tun daşọ mọ, ao fi gbogbo bi o ba tilọ ye arawa, ọna ti yio ba gba, ao jẹki ẹ mọ bi o ti wu ki o ri ọmọ ma ku, ọmọ yio ye awọn janma, nwọn a şi ki iya ọmọ ku ewu, nwọn a si ni Ọlọrun ko ba a wo pẹlu,

A ko ni ireti pe Ijọba tun le ti sakani wọn da ọran owo yi silẹ, lai jẹ wipe awọn ẹniti ọran owo na ko tẹlọrun tun ronu kan eyiti nwọn tun le şe si i, gẹgẹbi ipinnu ti Igbimọ ti şe le lori niwaju Ọlọla Baddeley, ni Igbimọ ti nwọn şe gbẹhin lọdun to kọja.

Awa ko fẹ ọrọ nwon ni! nwọn ni!! *Them Saying! Them Saying!!* lati gbọ si eti irọ lo mbẹ ninu ọrọ nwọn ni, awa kosi fẹ ọrọ irọ lati gbọ si eti nitori nkan bi aiṣododo jinna si wa pupọ, Ọl'ọrun ma si jẹki a ri ohun ti yio mu wa joko sidi irọ, awuzu-bi-lai, ki Ọlọrun ṣọ wa nibẹ.

Ohun ti o mu wa sọ gbolohun nipa ti ọrọ nwọn ni ti a wi ni wipe, o jẹ aṣa ti nwọn ma nda ni ilu yi ti a nfi eti arawa gbọ ju lẹnu awọn ara ilẹ yi papa awọn ẹniti ko yẹ arara, lati wa ni idi irufẹ aṣa bẹ, gẹgẹbi ipo ọlọgbọn diẹ ti a fi ẹlomiran si, irufẹ ede bẹ, kosi ohun ti o le tun ṣe, afi ki o ba nkan jẹ, ni papa, ọpọlọpọ nkan lo ti baje fun ẹlomiran ti nwọn ko mọ, o jẹ aṣa ti o nda ilu ru, ti kole jẹki ẹnu ilu ṣọkan arara, nitorina li awa tiṣe ma mba irufẹ awọn ẹniti o ba ngbe lankẹ ọrọ ti ko han gedegbe to wi.

Ọpọlọpọ isọkusọ ni a ngbọ lẹnu awọn ara ilu ti nwọn nsọ nipa ọran owo yi, papa lẹhin ti Gomina Agba ti ilu Oyinbo de, irufẹ isokusọ bẹ, ẹlomiran ko mọ ewu ti o mbẹ nibẹ, ọrọ ti ẹ ba ri ka ninu iwe-irohin sakani wa nihin tabi eyiti awa na ba kinrin nibẹ i ba wu wa, ti ẹ ba le ma mu gẹgẹbi ododo ọrọ, eyiyi fẹrẹ san ju lankẹ ọrọ nwọn ni, ti ẹ fi ntan ara nyin jẹ lọ.

A fẹ ṣe gbogbo ohun ti nwọn ṣe ni Kansulu loju kan, a ko fẹ ki a sọ ọkan tan, ki a tun ṣẹṣẹ pada ranti omiran lati sọ, eyi nmu ai tete yẹ ọrọ ba ẹlomiran ṣugbọn ti a ba sọ bi gbogbo nkan tilọ si loju kinna, iyẹn dara julọ; titi ọsẹ meji si tabi bi iṣẹ ti a ni ṣe lọsẹ to mbọ, bi ko ba pọ, a le fi si igba na.

## IPINNU IJỌBA.

Irufẹ ipinnu ti a gbọ wipe Ijọba ṣe si ori ọja Siga fun fi-fowo-kun owo-bode re ni Igbimọ ti nwọn ṣe yi, ko ye wa arara, eyiyi mu ki awọn Oyinbo Onişọwo bu owo le Siga ati Tobacco (Sarotu) titi o fi mu ki awọn enia dudu papa fi ake kọri lati din bi nwọn ti nta ri ku sẹhin.

Ki a to sọ bi gbolohun kan si, ẹ jẹki a ro ẹjọ na fun nyin ki gbogbo wa si gba ọran na yẹwo, ki a si da gẹgẹbi sẹria ki iṣẹ ni dida ẹjọ mo da o gẹgẹbi ida alai ni lakaye li a nwi arara, bẹni ki isi iṣe dida, ko kewu ko bere a fẹ ki ẹ da si ikun ara nyin ni ti sẹria ti awọn Alikali nda, Alikali ti o ba tẹlẹ ilana Ọlọrun.

Enikẹni eyi owu ti o le şi Ṣabu ohun jijẹ ti a mọ ni Provision silẹ, ti ko ba ni Siga tabi Sarotu ni ṣobu, awọn o-mu, nwọn a ni kini oluwarẹ nta, ati pẹlu siga lo ngbe Ṣọbu awọn oni Provision niyi, lai si Siga nibẹ Okibo lo jẹ fun awọn ẹlomiran.

Ninu ohun gbogbo ti o nta fun awọn onişowo ijagba nja wo ju, Siga ni olubori, bi nwọn tiṣe nra Siga, ati Ewe-taba, o yatọ si bi nwọn tiṣe nra Apoti ọṣẹ Oyinbo, Karosini, Işana, Abẹla, Sadini, Miliki, Bọta ati awọn ohun omiran 'yoku iyatọ mbẹ fun olukuluku wọn, ṣugbọn Siga le fi ogun rẹ gbari pe, on lo nlọ julọ, tabi nyara ta, ti a ba si fi eyi ṣe abusọ, ki ẹnyin Profiṣọnnu jọwọ ki ẹ foriji wa o a kole mọ ẹsọ ju ọsọ lọ.

Bi o ba ṣe wipe awọn Ijọba nfẹ ṣe gẹgẹbi fẹ sọ yi, ki iṣe ọja ti o ba jẹ onjẹ ilu julọ, ki nwọn fi kun owo-bode rẹ, loju ti awa patapata gba li yio jẹ ọpọlọpọ iru awọn nta nkan wọnyi ni ṣọbu, ohun ti o ba si mu ba awọn enia dudu to nşowo bayi, nkan lati ba awon Oyinbo onişowo pẹlu.

Ẹlomiran nisisiyi lara awọn ẹniti oye wa loni ye daradara, nipa ai si owo-nina ọpọlọpọ, eyiti nwọn npe ni Ko si owo ni'lu, fẹ lati ta ọja Siga ti nwọn bu owo-bode ni ero wipe nwọn ki yio ra, bi nwọn ti a kole ba irufẹ awọn ẹni bẹ wi arara, kosi o nşowo ti ko fẹ ki on jere, ṣugbọn nigbati ko sure si ọja oluwarẹ kilo tişe le ta debi fi ri ere jẹ? Ẹ ba wa dajọ na ki a gbọ.

Bi a ba ri awọn ẹniti inu rẹ ndun fun fifi owo-bode kun Siga ati Sarotu, a jẹ wipe ẹlomiran ọpọlọpọ rẹ ni ile tẹlẹtẹlẹ ki owo to gon u, si mura lati ta wọn gẹgẹbi o ba ti da lode.

Ẹnyin onişowo ẹ mura lati gba ọran yi daradara, ki ẹ si jẹki o ye nyin gẹgẹbi ilẹ ti wa; awa ki iṣe Onişowo-Siga tabi Elewe-Taba, ṣugbọn a nso ti ai ṣe dede ti yio mu wa ni ikẹhin. A dupẹ lọwo Ijoba fun owo bode ti nwọn lori ohun jijẹ, Ọlọrun ko fun wọn ni lada.

## ANFANI WO NI ẸKỌ IWOYI NṢE?

Bi ọrọ ba ti ngbe ẹlomiran ninu lati sọ iwe-irohin, tabi bi oniwe-irohin omiran ko ohun ti yio sọ, ọrọ iwe-kikọ di abahun iyẹn ni nwon ti fi nşe orin kọ, Ọlọrun ṣe şofin gẹgẹbi ọran iwe ti nwọn nkọ ni Şukuru tilọ, iyẹn na to işẹ.

Ọran owo-ori wa ni ilẹ olubori ọran gẹgẹbi ti kosi lode fun awọn enia ati ọmọ wa papa ilẹ yi, a ko sọ iyẹn, a fi ẹtẹ silẹ a npa lapalapa.

A nkigbe wipe Ijọba ko fẹ ki awọn ọmọ anfani iwe mimọ gẹgẹbi awọn ara atijo, a ni nso wipe oju ilu tubẹ nla si, bẹni ọgbọn nwọ'nu ọgbọn, a nsọ wipe ko dara arara, awọn Ilana ti Ijọba ṣe le lori, a si nsọ wipe ko fẹ ki awọn ero ẹhin yi mọ iwe tobẹ mọ, tikalarawa ri wipe ki işe ohun ti o yẹ arara, eyi ni Ọlọla Lọya Eric Moore nja fun ni Kansulu kan ti nwọn ṣe lọ larin Ọdun to kọja.

Ebi npa ẹ nisisiyi, ọlọṣẹ wa nkiri, bi ẹ ko inu bawo ni ẹ o tişe wẹ ode, bẹni ọran na si loju wa.

Bi enia ba fi ọmọ si ile Ẹkọ ki a tilẹ ko ti pe Ijọba sofin kan nwọn ko sofin kuro, o daju pe owo ni oluwarẹ ni lati san fun awọn Tiṣa ti o mbẹ ni Ṣukuru yala, ni Ṣukuru kekere tabi giga; bi Tisa ba ya iwe-owo ti ẹniti o nkọ iwe yio san loṣu kan tabi loṣu mẹta ti nwọn tun nko laṣa, lori bi nwọn ko ba ri owo san, awọn Tiṣa ile-ẹko ni agbara lati pe ẹniti o ran ni lọ si ile-ẹkọ na lẹjọ lati gba gbese ti o jẹ Ṣukuru, bibẹko, nwọn le da ẹniti o nkọ'we dùro lati wa si Ṣukuru titi yio fi ri owo rẹ san, ẹniti a le si ode pe ko ri owo san, ti iwe si wu u lati kọ ọna wo lo le gba ni aye kọ iwe? Tabi ti o ba jẹ wipe ile-iwe na lo mbẹ lokan oluwarẹ lati lọ kọ iwe kilo tiṣe le kọ iwe mbẹ, nigbati ko ri owo san fun awọn olukọ?

A ko fi ero si ori iyẹn lati sọ, a nsọ wipe Ijọba sofin kan, ofin ti a ntẹnumọ yi, kosi ẹtọ kan nibẹ fun wa ati awọn iran ti mbọ lẹhin ti nwọn yio fẹ lati toju iwe kikọ daradara ṣugbọn nwọn ko ba iwe na nilẹ lona itẹlọrun tabi ni irowọ-irọsẹ gẹgẹbi awọn iṣaju tiṣe kọ tiwọn, a ko sọ wipe eyi jẹ arara, ju gbogbo rẹ lọ a ṣi nwoye awọn ẹniti o npe arawọn ni Ọṣẹlu ni ko jẹki a ti mu ohunkohun sọ lori rẹ.

Ṣugbọn lode ti oni oran owo ti ao fi gbọ bukata ni olukuluku nba ja, ọpọlọpọ ọmọ ni nwọn ti le wa ile nipa alai ri owo san fun awọn Olukọ, ẹwẹ ogunlọgọ enia ni o si ntẹ ki ọmọ on lo kọ iwe bi ko tilẹ ni fi ṣiṣẹ ko ṣa fi mọ oye diẹ lọna ti iya ki yio fi jẹ on, elomiran si lẹ ki ọmọ on mọ iwe tulasi, nigbati on obi rẹ tile ma gbọ agogo Ṣukuru lojo kinni ti on si tile pe ni agogo ina to njo o, ironu bi on yio tiṣe le ma ri owo ile-iwe san fun ọmọ on lo nka ọpọlọpọ lọwọ ko nigbati omi ba ti pọju oka lọ eyiyi ni bi bukuta ti oluwarẹ ngbe ni ile ba ti wọ oluwarẹ lọrun.

O mbẹ ninu ọmọ elomiran nisisiyi ti o nfẹ wipe bi on ba ti ka Standard V iwe ẹkarun tabi ẹkẹfa, ki on si tun lọ ṣe pẹpẹfuru ti o ba tun ku ni ile-iwe-giga bi Grammar School Boy's High School, tabi ni King's College lẹhin eyi, ki on gba iwe-ẹri (Testimonial) ti on ba lọ ṣe idanwo Ijọba, ki on ba le tete ri iṣẹ ṣe tabi Ijọba tabi lọdọ awọn oyinbo onisowo, ṣugbọn nigbati awọn obi rẹ ko ri aye lati ṣe atilẹhin fun ọmọ wọn gẹgẹbi ifẹ rẹ, kilo tiṣe le mu ọna gbogbo ti a ka silẹ wonyi ṣe? A fi ọna wonyi silẹ a ko ronu de ibẹ a nfi gbogbo ojọ sọrọ sinu iwe wipe Ijọba sofin kan.

Loju ti awa, a kole sọ wipe anfani kan ni eyi le ṣe, aiyafi ki a ba Ijọba sọrọ bi nwọn tiṣe ma dide si ailọdede owo ati iṣẹ ti ko si ni ilu eyiti o nmu ki ọgọrọ ọmọ enia nrare kiri ilu nipa a nwa iṣẹ labẹ awọn onisowo ati labẹ Ijọba lati ṣe, ti nwọn kosi ri arara, bikoṣe ẹniti o gba iwe-ẹri pe on yege nigbati on ṣe idanwo labẹ Ijọba, awọn elomiran ma ngba iṣẹ ẹniti o ma ba Administrator eyiti Ijọba yan gba owo (Income Tax) loṣu to mbọ.

Ẹ gba eyi ti a wi yi yẹwo, bi o ba jẹ ohun laifi fun iye ẹnyin ti ẹ ntẹnumọ oran Ẹkọ fun awọn ọmọ wa, tabi bi o ba jẹ gasikiya ẹ foriji wa.

Kosi ohun meji ti a ro ti o ju gẹgẹbi oye ti a fihan nyin nipa rẹ lo o dara ki a ronu kan ohun ti yio ṣe ilu lanfani, ki a si sọ bi o ba ti jẹ, ki awọn ẹniti yio ka ohun ti a sọ si ri gbangba daju pe ohun ti eleyi sọ ọrọ pataki ni, eyi lo njẹ iṣẹ iwe-irohin fun olotu iwe-irohin tabi fun awọn ẹniti o ba nsọrọ sinu rẹ, lai si eyi nibẹ ki a fi ọro pataki silẹ ki a ma sọ ọrọ ti ko moyan lori kan, bi ẹniti o fi ẹtẹ silẹ to npa lapalapa ni, ẹ maṣe gbọ wa si odi a ko sọ wipe oran Ẹkọ mimọ ko yẹ, ko ṣanfani ẹ lọ sọ wipe Kekere-Awo ma tun fọ omiran julẹ, o ma sọ wipe lati kọ iwe ki iṣe ohun ti o mọyan lori. Bẹkọ arara. a ni ọpọlọpọ ọmọ enia lo nwa iṣẹ lode nisisiyi ti nwon mọ iwe daradara lati fi ṣe iṣẹ kiṣẹ ti a gbe fun wọn ṣe, ni Kotu tabi ni Sẹkiteriati, ti nwọn kosi ri aiyafi ki nwọn yege ninu idanwo ti nwọn ba ṣe labẹ Ijọba, bi ọro tijẹ ni iyẹn o.

## IṢE AWỌN OYINBO-ONIṢOWO, NIPA OWO.

A tilẹ nsọ a nsọ wipe kosi owo kosi owo gbogbo nkan ko lọ dede mọ, owo ṣiṣe yi ko lere mọ fun awọn onisọwo oyinbo ati awọn enia dudu papa, eyiti awọn oyinbo onisọwo papa nṣe nibẹ lo nj'ohun.

Bi enia ba fẹ sọrọ, o yẹ ki o fi lakaye ati ọgbọn si ohun ti oluwarẹ yio sọ daradara, ki o ma sọ ohun miran ti kosi, ti nwọn o fi ho bo oluwarẹ pe yegede ko tan nidi rẹ na.

Ọpọlọpọ igba ni a fi nsọro nipa oran owo yi sinu iwe, gẹgẹbi itara ti a ni fun awọn onisọwo funfun ati dudu, awọn Ijọba si ni a ndi ẹru ọrọ yi ru pe nwọn mọ ohun ti nwọn le ṣe si ti iṣubu owo ati ai ri iṣẹ ṣe nwọn ko fẹ ṣuja n, a si nsọ fun wọn wipe ọrọ owo-ori lo ngbe wọn lokan ga lati ṣe gẹgẹbi iṣẹ ti nwọn ri wipe o tọ lati ṣe fun ilu, ti yio si jẹ nkan anfani fun wọn, ṣugbọn lati bikita fun iru babu ti ilu mbẹ nisisiyi nipa owo ati iṣẹ ṣiṣe, a ro wipe o jẹ ohun ti ko kan wọn arara bi nwọn ba ti nri owo-ori gba ọran ti buṣe, ṣugbọn nwọn ko fẹ bere, bi o tiṣe ṣiṣẹ ki o to ni owo lọwọ, tabi iru wahala wo ni oluwarẹ ṣe ki o to di Ọga ni Duwati, ani tabi bi iyẹpẹ ni oluwarẹ sọ di owo bi iṣẹ ogun ararẹ oluwarẹ na ni.

A kole sọ wipe Ijọba ko gbọ irn ọpọlọpọ ọrọ bẹ ti a nba wọn sọ, ti nwọn ba gbọ, a kole sọ wipe nwọn ko mọ ohun ti nwọn le ṣe si ti yio fi gun, gẹgẹbi ilu ti nfẹ, ṣugbọn nwọn ba da ni lohun pe o to gẹ, o yẹ ki awọn dide si ọran ti o tilẹ ndun awọn ọmọ wọn wọnyi lẹmi, boya nwọn si nṣe ṣawura nipa rẹ ni "Executive Council" a koi fi gbọ ni Igbimọ-Aṣofin ni ki awọn Aṣoju ilu mẹtẹta si

fi si eti igbọ ilu, tabi ki awọn papa fi sinu "Gazette" gẹgẹbi nwọn yio ti ṣe.

Ọna wo ni gbogbo nkan fi le lọ letoleto fun eniti nṣowo, nigbati a ko ba fi ero si lọtun ati losi, lai si wipe awọn ẹnikan nrẹ ẹnikan jẹ, ani lai jẹ wipe awọn ẹnikan nfẹ lati ma da gbese si ẹnikan lọrun.

Nitotọ Ijọba ngba owo-bode lori ẹru ti o ba de de si Bode (Custem) awọn Bank yio gba tiwọn nibẹ ti nwọn ba fi ẹru ṣọwọ si sakani wọn, awọn oyinbo Ọlọkọ yio si tun gba owo ọkọ tiwọn nibiti nwọn ba gbe ti fi ẹrn ṣọwọ, gbogbo iru inawo bẹ lo ndi ọja lọwọ lati ri ere to gẹgẹbi olukuluku ti nfẹ.

Nigbati awọn oyinbo kan ba de ti nwọn ba ṣi Ṣọbu kalẹ, nwọn fi ṣi silẹ fun gbogbo aiye lati ra, awọn tani ha nra ọja ju tabi ti nwọn nba oyinbo ṣowo pọ ju bikoṣe awọn enia dudu, ki a tilẹ ni awọn oyinbo nba ara wọn ja, eyi ki iṣe irọ arara, iba ohun elo ni oyinbo nra, oyinbo kole ba oylnbo ẹgbẹ rẹ ra ọja lati ma ta nihin, afi ni ilu wọn lọhun ni nwọn gbe nṣe bẹ.

Ohun ti o si nmu wọn ṣe bayi ni wipe ti ọkan ninu wọn ba dide ti o ba fi owo kalẹ, ohun ti ọkan ko ba ni, o le lọ ba ekeji rẹ ra lati fi kun Ṣọbu tirẹ ati fun titun-ta, ṣugbọn mo fẹ ma wa ba ọ ṣowo, ki nma ra ọja lọwọ rẹ lati ma lọ ta, tabi ki nma gba awin ọja ki nsi ma mu owo wa lori eyiti mba nta, oyinbo kan ko jẹ ṣe bẹ lailai, boya nwọn si nṣe bẹ ni sa yi a ko mọ nitori aiye ti lu jara.

Awọn enia dudu lo nmu Ganrandi ile wọn ti nwọn nru lọ ba oyinbo pe ki o ma ko ọja fun lati ma ba wọn ṣe owo pọ

Ti nwọn ba si gbọjẹgẹ eyi pẹlu wọn tan, ti nwọn nko ẹru fun arawọn, eyiti o ba ta yio ma lọ sanwo rẹ, eyiti ko ba ta, nwọn yio ma mọ bi o ba ti nlọ si ninu iwe ti nwọn ba fi nba 'rawọn ṣowo, iwe ti nwọn npe ni Pass Book.

Bi o ba ma gbọ, nwọn a ni lagbaja da gbese lọdọ oyinbo bayi-bayi nwọn ta ile tamẹdu ọna wo ni enia ko fi le digbese?

Bi oyinbo omiran ba ko ọja kan fun onișowo wọn kan tan ni iye kan, ti yio fi rọju diẹ si ti awọn oyinbo papa lati ta nigbati o ba tun ṣe, nwọn a wo ṣuṣu nwọn a yọ bi elo kan kuro lori iye ti nwon ti pe fun awọn Onișowo wọn ri, nipa eyi ko ni le jẹki awọn Onișowo wọn ri oju owo ambọsibọsi ere, tani jẹ fi ibi ọpọ silẹ ki o lọ ra ọwọn? O li Dani ọlọra, ti oyinbo omiran ba si ri wipe awọn ti ta iru ọja na tan, nwọn le sọ wipe kiloșe ti oluwarẹ ko tete da pada, nigbati o mọ wipe ko lọ, nwọn a fi ake kọri pe awọn ko ni gba mo, tulasi o ni lati di gbese si oluwarẹ lọrun, bi oluwarẹ si ni o nṣe fitafita kan o ntan ararẹ jẹ ni, nipa bayi ni awọn enia dudu tiṣe ndi onigbese ọsan gangan lọdọ awọn Oyinbo onișowo.

Ni ọja Ejinrin, Agbadayigi ati awọn ọja gbogbo ti nwọn nna li a gbọ wipe awọn Oyinbo onișowo nlọ si Ṣọbu si ti nwọn nta ọja, ti nwọn si nra Ekurọ pẹlu, a tilẹ gbọ wipe nwọn ti buraka si Ejinrin nisisiyi, nipa eyi nwọn ko jẹki awọn enia dudu ri ọwọ yọgbe mọ, wahala pupọ ni awọn enia dudu nṣe nisisiyi lọna ọja wọnyi ati ni ile ki nwọn tole ma ri ere diẹ diẹ jẹ lori ọja wọn; iṣẹ ti o wa ni ilẹ fun wa lowọlọwọ yi pọ, nitorina a lẹ fi alamọri sisọ ọrọ yi ni kikun si titi ọjọ mẹta lagbara Soko.

Emi ni tiyin nitotọ,
KEKERE AWO.

---

## ORI II.

## IWA—AGBARA TI ẸKỌ ILE NI.

*( Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KẸTALA.

A sọ ti iya Washington pe ẹniti o mọ ọwọ yipada ni; ki isi ṣe pe mimọ ọwọ yipada yẹ obinrin ti o ba jẹ obinrin totọ nikan ni, ṣugbọn a ko le ṣai ni i larin ile nitori ki a ba le ni irọra ati anfani. Ki a mọ ọwọ yipada ki iṣe lọna ti ọja tita tabi ti iṣẹ-ṣiṣe nikan, ṣugbọn ti ọna gbogbo gbà ti a gba ṣe nkan ninu aiye—lọna ti ohun gbogbo ti o ba ni eto ninu, ohunkohun ti a o ba ni lati pese silẹ fun, ohunkohun ti a ba ni lati ṣe. Ninu gbogbo ọna ti a ka silẹ wọnyi, bi ibojuto tabi itọju ile-ọja tita ti ri bẹna ni ti inu ile ẹni si ri pẹlu. nfẹ eto, aipakasọ, ipalẹ, iṣẹ, ifi ero lu nkan, ikamba ara-ẹni, èwé, imọ, ati ọna ti a fi nmu nkan dọgba. Gbogbo iwọnyi ni o jẹ pataki ninu iṣẹ òwó-ṣiṣe tabi ọja tita; nitorina ni bi obinrin yio ba ja fafa ninu iṣẹ ile titọju, tabi ti yio mu idunnu wa ninu ile, ko le ṣai kọ gbogbo ọna iṣẹ òwó-ṣiṣe tabi ọja-tita-bakanna bi ti ọkunrin lọna iṣẹ-ṣiṣe tabi lọna òwó-ṣiṣe.

Ṣugbọn a ti ma nro ri pe nkan wọnyi ko kan obinrin, ati pe ọkọnrin nikan ni ẹkọ iṣẹ tabi òwó-ṣiṣe kan. Ẹ jẹ ki a mu ti ẹkọ iṣiro (figures). Mr. Bright sọ nipa ti awọn ọmọ-kunrin pe, "Kọ ọmọ-kunrin ni ẹkọ iṣiro faufau, ọmọ na pegede, o di on nun."

Kiloṣe?—Nitoripe eyi a kọ ọ ni eto, aipakasọ, iye owo, iwọn, ati bi nkan ti ri si ara wọn.

Ṣugbọn awọn ọmọbinrin melo ni o mọ ẹkọ iṣiro faufau? Ni gasikia diẹ ni a le ri. Ki si ni agbare-gbabọ eyi? Nigbati ọmọbinrin ba wọle ọkọ, ti ko ba ni ẹkọ iṣiro, ti ko ba mọ aropo owo (addition) ati iye ti iye bayi ni ọna bayi jẹ (multiplcation), ko le ṣe iṣiro owo ti o nwọle ati eyiti o nna, ko si le ṣe ki o ma ṣe aṣiṣe gburughu

lọ eyiti o le mu ede-oyede wa ninu ile. Nigbati obinrin ko ba ja fafa ninu iṣẹ rẹ—eyini ni, ti ko ba mọ ọna ẹkọ iṣiro lati le mu nkan gun ninu ile—nipa aimọ ko le ṣe ‘ai na inakuna, eyiti o le mu iya ati aigbadun wa ninu ile.

Bi eto ti jẹ ẹmi iṣẹ-ṣiṣe tabi owo-ṣiṣe, bẹna ni o si jẹ pataki ninu ile. Eto ni a fi iṣe iṣẹ yanri. Idarudapọ ati apabo ko ri ibi duro lẹgbẹ rẹ. Eto nfẹ ki a ma tase akoko, eyiti o tun jẹ nkan pataki ninu iṣẹ-ṣiṣe tabi owo-ṣiṣe. Obinrin ti o ntase akoko nwa ki a pa on ti (gẹgẹ bi a o ti pa ọkunrin ti o ba ntase akoko ti) nitoripe a ma lo akoko danu, a si mu ni ro pe o nda agunla ẹni ati pe a ko to ẹniti o le mu on ṣe nkan ni akoko. Owo ni akoko jẹ fun Oṣiṣẹ-ọkunrin, ṣugbọn fun Oṣiṣẹ-obinrin eto ni o ju—eyi ni iṣe alafia, irọra ati igbadun ninu ile.

Bi o ti jẹ pe ki enia mọ agbeka jẹ ọkan ninu ohun wọnni ti o jẹ pataki lọna iṣẹ fun ọkunrin, bẹ na si ni fun obinrin pẹlu. Ki a mọ agbeka jẹ ọgbọn san, ero ni isi mu eyi wa. Ki a mọ agbeka ninu ohun gbogbo jẹ bi o ti tọ ati bi o ti yẹ, ki a fi ero lọna ti o tọ lu ohun ti a fẹ lati ṣe, ki a si ṣe ohun na lọna ti o tọ. Agbeka a ro ti ohun ti a o mu ṣe nkan, eto ti a o fi to o, akoko ati ona ti a o fi ṣe e. Eyiti oju ti ri ni ikọ ni agbeka, imọ a si gbe agbeka yọ.

Nitori ohun ti a sọ wọnyi ati awọn miran ti a ko sọ, o yẹ ki gbogbo obinrin kọ ọna iṣẹ-ṣiṣe ki nwọn ba le jẹ oluranlọwọ ti o to ninu aiye. Ẹwẹ, ki inu ile ba le ni lari, awọn olorin bi alabojuto ikoko, awọn ti o ntọ ọmọ ati awọn olukọ awọn ewe, ni lati kọ ẹkọ iwe mimọ lọna k’ọna ti eyi le fi jẹ iranlọwọ fun wọn ninu iṣe wọn Ifẹ ti a da mọ ni nkan ko to.

Eyiti awọn ẹranko nlo tabi ti nwọn fi ntọju ara wọn ko ṣẹṣẹ di igbati a fi kọ wọn; ṣugbọn ọgbon tabi oye ori enia, eyiti a nlo nigbakugba larin ile, nfẹ kikọ.

Ọlọrun fi ti ara lile awọn ọmọ ti a nbi le obinrin lọwọ; ara si jẹ igbalẹ ninu eyiti a fi iwa ati ọgbọn ori pamọ si. Nipa titẹle awọn ofin ẹda, eyiti obinrin ni lati kọ ki o si mọ ki o to le tẹle wọn, ni a le fi ni anfani ara lile, ogbọn ati iwa ti o peye ninu ile. Aimọ awọn ofin wọnyi a sọ gbogbo ifẹ tabi ajo iya lori ọmọ di pabo, ere iya a si jẹ ti alabiku.

Gbogbo wa ni a gba pe, a fun ati obinrin ati ọkunrin ni ẹbun ogbọn-ori fun lilo ni, ki iṣe pe “Ki o gbe inu obinrin ra si.” Ẹbun iru eyi ki iṣe fun lasan. Ẹlẹda le lawọ niti awọn ẹbun Rẹ ti O nfi fun ni, ṣugbọn ki iṣe apa.

A ko da obinrin ni alagbara ma mọ ero tabi ni ohun ẹyẹ meremere fun faji ọkunrin ṣa. A da o si wa fun ara rẹ ati fun awọn ẹlomiran pẹlu, iṣẹ nlanla ti a si pin fun laiye nfẹ ẹkọ ọgbọn ori ati ọkàn ifẹ. Olubori iṣẹ rẹ laiye ki iṣe kikọ awọn ẹkọ onipẹpẹ-furu eyiti a nfi gbogbo akoko ti a ba lo fun ẹkọ miran kọ; pẹpẹfuru le yẹ igba ewe ati ẹwa oju, mejeji yi won ni to fun ara wọn bi fifi pẹpẹfuru ṣe ẹjọ wọn, ṣugbọn ti o ba di ti nkan pataki, iwọnyi ko de ibi kan.

*Translated By*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---


# “PARUNPỌ”

ni orukọ Iwe Egbogi titun kan ti agbajọ awọn Ẹgbẹ Onişegun kan ni Abẹokuta ṣe.

TABI TABI KO SI NINU RẸ

PARUNPỌ GAN NI.

**6/6d** ni tita rẹ

(Owo lati fi ranṣẹ si ilu ọkere 6d).

Ẹ o ri ra ni “Tika-Tore” Press, Broad Street, Lagos, ati lọdọ:—

JOHN ỌDUNTAN,
Ijeun, Abẹokuta.


---

**CHANGE OF NAME.**

S. A. COLEMAN-DANIEL

TO

ADENIJI ṢOYỌMBỌ-ABỌWABA.

Commencing from the 1st day of February, 1928, the public are hereby notified that I, formerly known as S. A. Coleman-Daniel, do now desire to be known and called by the name

**ADENIJI ṢOYỌMBỌ-ABỌWABA.**

**All documents bearing my former name remain valid.**

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, MARCH 3, 1928.

## ARI GBỌDỌ WI, IKUN NI 'MU EGBERE.

Owe yi ni a le pa si Iwe ti Aṣoju Eko W. Birrel-Gray fowọ si ninu *Gazette* ti Ijọba ti ọjọ kẹtalelogun oṣu ti o ṣẹṣẹ pari yi ni ewe 118 nipasẹ ti owo asingba ninu eyiti a ri ka pe ẹnikẹni ti o ba kọ lati sọ ohun ti Ijọba nbere lọwọ olukuluku nipasẹ ti wiwa oluwarẹ ati dukia ti o ni ti a le ṣiro owo asingba ti yio ma sanwo le lori, lẹhin igbati awọn Oniṣẹ Ọba ti a ti yan ba bere lọwọ oluwarẹ tan, yala ni ọrọ ẹnu ni tabi nipa gbigba ọrọ oluwarẹ sinu iwe ti Ijọba ti tẹ fun irufẹ iṣẹ bẹ, tẹtẹ ọgọrun pọnun (£100) tabi ẹwọn ọdun kan ni yio jẹ oluwarẹ; ara ilu, ki l'eyi, bikoṣe oko-ẹru ẹkeji, eyiyi ko ha ju ida tabi ibọn ti awọn alagbara nlo nigba lailai lori awọn ti nwọn ba tẹ ni gaba lọ. Nigbati a ba paṣẹ fun onile ọlọna kan pe tulasi ati dandan-gbọn ki o yara bẹrẹsi ka gbogbo ohun-ini rẹ fun Ijọba ki o ma si ṣẹ ọkan ku nibẹ, bi bẹkọ iya ọgọrun pọnun (£100) ni sisan ni waraṣẹṣa sapo Ọba nro ati ẹwọn ọdun kan, ẹ ko ṣai mọ pe oluwarẹ di "ẹru" Ijọba apapandodo niyẹn; Ijọba kọ lo ba ẹ ṣiṣẹ dukia rẹ ti o ni, iwọ ko ṣai sanwo bode lọnakọna fun gbogbo owo ti o nṣe tabi gbogbo ọja ti o nta, sibẹsibẹ Ijọba sofin owo asingba pe ọran iyan ni fun ọ lọdọdun lati ma san owo asingba titun yi ti o ti di asan-isan-tan owo ologbo.

Ni koi pẹ yi ni awọn kan nfi tẹduntẹdun sọ pe kini anfani (*advantage*) ti o mbẹ fun ilu Eko gidi lati ni aṣoju mẹta ninu Igbimọ Aṣofin Ọba bi irufẹ awọn Ọlọla mẹta ti ilu ni nibẹ nisisiyi, nigbati o jẹ pe bi o ti wu ki awọn aṣoju mẹta yi sọ sọ sọ to, ki nwọn si ma ja fun ilu loju mejeji lati fi ohun ti o nni Eko ati agbegbe rẹ lara han, pabo ni, ọrọ awọn Ijọba ni yio ṣẹ, bi ko ba ṣe bẹ ni kini ṣe ti Ijọba ko fun ọkan ninu awọn aṣoju wa wọnyi laye ni oṣu diẹ to kọja lati ka Iwe-ẹbẹ (*Petition*) ti a gbọ pe awọn ara ilu kan leti Eko kọ si Ajọ Igbimọ Aṣofin yi nipa ọrọ kan ti o jẹ ẹdun wọn, Iwe-ẹbẹ ti a gbọ pe nwọn fi ran ọkan ninu awọn Aṣọjn Eko mẹta na pe ki o ba wọn ka fun Ajọ Igbimọ Aṣofin na; lẹhin, a ṣebi nigbati o kan Iwe-ẹbẹ na ni kika, ọpa kan ni Igbimọ fi bi wo pe awọn ko yọda kika Iwe-ẹbẹ na, lẹhin igbati nwọn ti dibo fun kika rẹ; a ṣebi awọn ti nwọn na'wọ soke pe awọn ko fẹ kika iwe-ẹbẹ na pọju awọn ti nwọn na'wọ soke fun kika rẹ lọ, ọrọ re o. Ẹnyin ẹ tun wo inu iwe *Gazette* kanna yi, ewe 11, ẹ o ri bi Igbimọ ti fi ọpa kan bi aba (*Motion*) ti Ọgbẹni K. Ata-Amonu, Aṣoju Calabar, mu lọ si Igbimọ na wo, lẹhin igbati Ọgbẹni Eric O. Moore ti gbe aba na lẹsẹ tan; gbogbo nkan bawọnyi ko le ṣai ṣọ ẹnikẹni ninu tobẹ ti ẹlomiran fi le sọ pe iwa elekuru gbọn yẹyẹ kan ko ju eyi lọ. A ko ṣai tẹriba fun ofin Ijọba, ṣugbọn eyiti o ba ni ilu lara lọpọlọpọ bi irufẹ ofin owo asingba yi ko jẹ nkan ti Ijọba le ni ki ilu gba bi nwọn fẹ bi nwọn kọ, fifi agbara ti ajaga ofin gbigba owo asingba yi bọ ilu lọrun dabi igbati ẹniti o ju ni lọ fi ọwọ nla gba ni loju. Njẹ ti a ba sọ pe iwa "ki lẹ ja mọ" ni irufẹ mimu ilu ni aberi-wẹrẹ lọna bayi, a ṣi wi bi?

Ni gasikia, a ti nri igba Gomina l'Eko nibi, ti Gomina Eko isisiyi yatọ lọju wa fun oniruru ofin ti o di akokoniko-apọnimajẹ fun ilu nisisiyi, awọn ofin ininilara bi ofin owo aasingba (*Income Tax*) ati Fito Ilu Eko (*Lagos Town Planning Ordinance*), eyiti nwọn ṣi nṣe akatakiti rẹ lọwọ ni Igbimọ; bi a ti nwi yi, a ko ṣai ri awọn elomiran ti nwọn ni inu didun si gbogbo ofin wọnyi ti nwọn si le ma ṣe a-ho o, abẹ-ntẹ, ṣugbọn ọkan ni, Atakoro wọ'nu ado ha le gbe ọmọ rẹ wõ bi?

Ọpa agbeleka,

T'ẹhin lo ju !!!

# EDE OYINBÒ ATI IṢẸ-ỌWỌ.

*(MANUAL LABOUR.)*

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU ]

Mo bẹrẹ f'oji

Nitori idi pataki ti ọpọlọpọ enia ṣe nkọ ẹkọ ni Ṣukuru ni lati le gbọ ede Gẹsi. Eyi ko buru rara, nitori, ni aiye ti a wa yi, ede ilu ẹni nikanṣoṣo ko tolo. O rẹrun pupọ fun awọn ara wa ti o n'ṣowo ni ilu Hausa, ti o si gbọ ede Gambari ju ẹniti ko gbọ lọ; bẹ gẹgẹ si ni ede ilu miran pẹlu.

Bi enia fẹ ti o kọ oniruru ede lati mọ, o dara; ṣugbọn awa ka a si iwa were fun ẹniti o gbọ orişirişi ede-el'ede, ti o si jẹ ọgbẹri ninu ede ilu tirẹ papa.

Ẹlomiran ninu awọn "Ọmọ Eko" ro wipe ohun pataki lati fi ṣe fuja ni wipe, awọn ko le ka iwe Yoruba tabi wipe, awọn ko gbọ ijinlẹ ede Yoruba, afi ede Oyinbo; iba si ṣe wipe nwọn gbọ ede Oyinbo na daradara, ki nwọn si le sọ ọ bi awọn elede ti nsọ ọ, ṣe iba san diẹ; ṣugbọn, ede Oyinbo, nwọn ko gbọ, ede ilu iya wọn, nwọn ko mọ.

A le sọ wipe ko nşe ẹjọ wọn tobẹ, ti nwọn ko ba le ka iwe Yoruba şaraşa, nitoripe ko da mi loju wipe a nkọ wọn ni iwe Yoruba tobẹ ni Ṣukuru; ṣugbọn sibẹsibẹ, a tanma wipe, o yẹ ki olukuluku ma ṣe ayan lati mọ ọ li ọnakọna. Bawo ni a o ti wi, ki Oyinbo kan sọ fun wa wipe, on ko le ka iwe Oyinbo, on ko gbọ ede Oyinbo, afi ede Yoruba! Irufẹ ipo yẹyẹ bayi ni awọn ti o sọ wipe awọn ko le ka iwe Yoruba nfi ara wọn si nigbakigba.

Bi o ti yẹ ki a mọ ede ilu wa, bẹ gẹgẹ ni o si tọ ki a kọ ede awọn Oyinbo ti o jẹ Ọba lori wa; ṣugbọn, nitori kini a tlẹ ṣe nja ijakadi lati gbọ ede Oyinbo? Ni aipẹ yi, a nba ọmọ kekere kan ti ko ju ẹni ọgbọn ọdun lọ sọrọ; nigbati a si bere lọwọ rẹ wipe, kilo ṣe ti o dabi ẹni wipe ede Oyinbo ya si i li ẹnu diẹ ju ede ilu tirẹ papa lọ? O si dahun wipe, *Please Sir*, nitori ati jẹun ni on ṣe ntẹra mọ ede Oyinbo ni siso, ki o ba le ma yọ l'ẹnu on nigbati on ba nba Oyinbo on sọro ni ibi iṣẹ; ti ko ba ṣe bẹ, bawo ni on ṣe fi ede ilu iya on silẹ l'ai kọ, ti on yio tẹra mọ ede-elede; ati pẹlu pẹlu, ede Yoruba ko ni a-sọ-fẹhinti bi ede Oyinbo. A bi i lere wipe, ewo ni o ñjẹ a-sọ-fẹhinti? O ni "Imposibiliti nkọ, Intẹgriti nkọ"? A si da a lohun wipe, a ko le fẹ irufẹ a-sọ-fẹhinti bẹ ku ninu ede Yoruba pẹlu; gẹgẹ bi apẹrẹ, a bi i lere bi o mọ itumọ ọrọ ti Yoruba npe ni "Ẹniab nibilabiniti"? Nigbana ni ọdọmọkunrin yi to gbagbọ wipe a-sọ-fẹhinti wa ninu ede Yoruba pẹlu.

Sibẹsibẹ, a ko ko ọrọ ti o sọ danu wipe, nitori ati ri iṣẹ ṣe, ti on yio fi jẹun ni idi pataki ti on ṣe kọ ede oyinbo; o si ro wipe nitori nkan kanna yi ni ọpọlọpọ ọmọwe ṣe nlọ si Ṣukuru pẹlu, nitoripe Oyinbo nikan ni a le ta ede wọn fun ni owo ti o jọju diẹ, owo pọ ọ ti ko ni lari ni Enia dudu nsan, iyẹn ti o ba tilẹ jẹ ra ede Oyinbo lọwọ rẹ lati fi tọju Iṣẹ tabi Ṣabu rẹ.

Gẹgẹ bi nkan si ti nlọ si nisisiyi, nigbati a ba nwoye ọmọ ti o njade kuro ni Ṣukuru li ọdọdun, lẹhin ti nwọn ba ti tan Kewu; ominu nkọ wa wipe ọpọlọpọ ninu wọn ni ko ni ri iṣẹ Akọwe fi ṣe; melomelo ni o ti nwa iṣẹ ṣe ninu won, ti o si jẹ wipe ibikibi ti nwon ba de, "*NO VACANCY*" ti şiwaju wọn de ibẹ! Eyi le jẹ ki ẹlomiran ro wipe o-ku-ta ṣẹ nde si ede Oyinbo diẹdiẹ. Yala bẹni tabi bẹkọ, o yẹ ki a kọ awọn ọmọ wa ni ẹkọ ati ede Oyinbo daradara, papa ede G.si, l'aibikita bi nwọn le fi ri iṣẹ Akọwe ṣe tabi nwẹn ko le fi ri i ṣe; lẹhin ti a ti mọ ede tiwa tan, ti a si jinlẹ ninu ẹkọ ati imọ Oyinbo, nigbana ni a le ba wọn fi pẹki-ko-pẹki, papa, nigbakigba ti ọrọ ilu ba de ilẹ.

Ẹko, ọgbọn, imọ, ati otitọ-inu ni o le gbe wa ga bi Orile-ede, a ko si gbọdọ da họ-ọ owo, eyiti apele rẹ njẹ Adeyanju.

Lẹhin ti awọn ọmọ wa ba ja-fafa ninu ẹkọ tan, nwọn le ṣe iṣẹkiṣẹ ti o wu wọn; ṣugbọn, igbala wa ko si ninu iṣẹ Akọwe to bi o ti wa ninu Iṣẹ-ọwọ (*Manual Labour*,) oniruru iṣẹ, bi iṣẹ Agbẹdẹ, Gbẹna-gbẹna, Aṣọ-riran, Ile-kikọ, Iṣẹ-agbafọ, Awo-mimọ, Ọṣẹ-şişe, ati orişirişi iṣẹ miran ti Oyinbo fi npada ko iba okan, eji, ti nwọn nfun wa pada lọ si ilu wọn.

Iṣẹ Loya, Dokita ati Sofiọ (Wọnlẹ-wọnlẹ) dara nitotọ, ṣugbọn gbogbo wa kọ ni o ni anfani iṣẹ wọnyi, ati ju bẹ lọ, ọmọ ẹhin ni awọn iṣẹ mẹtẹta yi jẹ li ẹgbẹ awọn Iṣẹ-ọwọ ti a ka silẹ wọnyi, fun ilọsiwaju wa gẹgẹ bi Orilẹ-ede. Ẹniti o ba kọ iṣẹ ọwọ ni ilẹ yi, ti o ba ni ipa rẹ, ki o tun lọ si Ilu Oyinbo lati lọ kọ ọ ni a-kọ-ye daradara.

Gbogbo owo ti Akọwe Ọba ngba, "alubarika" Iṣẹ ọwọ awọn Oşişẹ (*Artisans and Labourers*) ni nwọn fi ngba a; sibẹsibẹ, pupọ ninu wọn a ma fi oju tinrin awọn Oşişẹ wipe, "*Oh! They are nobodies, but common Artisans.*"

Ọpọlọpọ enia ni o si nro irokuro wipe, ẹniti ko ba mọ iwe ni o yẹ ki o ṣe Iṣẹ-ọwọ, nwọn gbagbe wipe iwe ti Oşişẹ ni lati mọ pọ pupọ ju ti Akọwe lọ, bi o ṣe wipe nwọn ri afo lati kọ ọ to gẹgẹ bi iṣẹ wọn ti nfẹ.

Ju gbogbo rẹ lọ, ko yẹ ki ẹnikẹni ṣa ede ilu iya rẹ ti, ko yẹ ki a ma ri Iwe-irohin Ilu Oyinbo lọwọ rẹyin li ọsọsẹ l'aika "EKO AKETE" ati Iwe-irohin Yoruba miran pẹlu, ko yẹ ki ẹ gb'ojule iṣẹ Akọwe nikan, ko yẹ ki ẹ jẹ ọgbẹri ninu ẹkọ ati imọ Oyinbo; bori-bori gbogbo rẹ, ko yẹ ki ẹ ma rena awọn Oşişẹ, ko si yẹ ki ẹ kẹgan Işẹọ-wọ,

nitori ninu rẹ pataki ni igbala wa wa gẹgẹ bi Orilẹ-ede.

Nigbati a ba kiyesi gbogbo nkan wọnyi li ẹsẹsẹ, nigbana ni a lẹ ma fọngā, nigbana ni a le ni ireti wipe, "*African shall rise*" nitotọ.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## OLUSAKIN'S COLUMN.

### Nigeria's Bright Prospects.

MEMBERS OF PARLIAMENT INTERVIEWED.

LONDON FRIDAY—The two members of Parliament, Major Walter Elliott and Captain Garro-Jones, who were members of the Parliamentary mission to Nigeria have arrived at Plymouth.

In an Interview Major Walter Elliott said he was impressee with the great possibilities of Nigeria and the bright prospects of the country's future. He emphasised that Nigeria will always remain a blackman's country and described the West African States as an Empire in themselves only comparable with India and they are still in their infancy. Captain Garro Jones was of the opinion that the trade of Nigeria with England is bound to increase by leaps and bounds in the future.

### Christening.

The christening ceremony of their Infant Son George Ibikunle Adebayo Phillips took place on Saturday the 25th February last by the Rev. M. S. Cole, M.A., at Christ Church Pro-Cathedral at 4.30 p.m.

The Sponsors were Mrs. Oyinkan Abayomi, Barrister Olaṣeni Moore and the Hon. Dr. C. C. Adeniyi-Jones who was represented at the service by his daughter Miss Remi Jones. Mr. & Mrs George I. Phillips were "At Home" on the same evening to few friends and relatives, several palatable dishes were laid on the table and drinkables were liberally served.

Conspicuous among those present were H. Macaulay, Esq., C.E., The Hon. Dr. J. A. Caulcrick, S. W. Dalley, Esq., of Abeokuta, Herr Atto Hamann, Agent of Arnold Schlesinger, K. Stark, Esq., A. B. Ojomu, Esq., E. A. Akigbehin, Esq., Misses Dalley, Moore, Smith and Akigbehin.

We pray that the life of the child may be spared.

### Tour of His Excellency the Governor and Lady Thomson.

His Excellency the Governor and Lady Thomson and personal Staff left Government House on Wednesday the 29th February last, on a tour of the Northern Provinces. His Excellency hopes to return to headquarters on the 18th of April.

### Resumption of Duty.

Mr. M. L. Adigun, 1st Class Clerk, Nigerian Railway Traffic Audit, Ebute Meta, who has been on two month's leave, has now resumed his duties as from yesterday the 2nd instant.

### Obituary.

The death took place at Ibadan, on Saturday morning, the 25th ultimo, of Mr. Abudu Mabinuori, alias Abudu Dawodu, Government Produce Examiner.

The deceased was a brother of Mr. Awesu Dawodu and relative of Messrs. J. K. Dawodu and W. A. Dawodu of Lagos. Our sincere condolence.

---

The death of Dr. John Randle, M.B., C.M., the oldest Medical Practitioner is announced as having taken place at his residence 31, Marina, Lagos, on Monday, the 27th February, 1928, at 11.45 o'clock in the morning.

Dr. Randle was up to his death President of the Peoples Union and of the Reform Club.

The funeral service took place the following morning at Christ Church Pro-Cathedral at 9 a.m., (and why not at his St. Paul's Church, Breadfruit). The Right Rev. Bishop Oluwole, D.D., and Rev. M. S. Cole, M.A., officiated.

To his son Mr. Jack Romanes Randle, and all other children of the deceased and the principal mourner his friend Henry Carr, Esq., I.S.O.,—Our sincere condolence.

Aged 73 years and 26 days.

OLUṢAKIN.

---


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ oju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le sẹsẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti ko ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o ma electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

## IBOSI OWO ! ! !

Lati nkan bi idunta wa, ṣaṣa ni ẹniti idamu ọda-owo ko ba; gidipa awọn oyinbo onișowo ti nwọn wa larin wa, awọn to jẹ pe a ko ro pe igba ais'owo lode yi le kọlu ni a le sọ pe nwọn tilẹ tete fagbọnmuja, nipa dida ti nwọn da pupọ ninu awọn oșișẹ ati awọn akọwe wọn duro lẹnu iṣẹ; a tilẹ ri Ile Owo awọn Oyiubo to mẹta mẹrin ti nwọn ti "Ko'gba sile" fun lilu ti nwọn lu igbese ni iwọn ọdun diẹ sẹhin.

A fẹ le sọ pe bakanna ni ọda-owo yi farahan ni'ṣẹ Ọba pẹlu; igba pupọ kọ ni a ngbọ pe a fa awọn ẹlomiran sipo ẹhin? Tabi ki a din nwọn ku ni *Office* nitori arun ailowo-lọwọ-baba-ijaiya to wa ni gbogbo aiye nisinsinyi.

Bi ẹnyin ọkawe wa ba w'ode isinsinyi, ẹ ko ha ni ri pe ọp lọpọ lo wa ti nwọn ti "nda bete" nipa didawa fun owo-ṣiṣe ri, ṣugbọn ti igbese ti da lọwọkọ tobẹ ti o fi jẹ pe tulas., oluwarẹ tun puda gba iṣẹ "*boy*" nipa didi ọmọ abẹ oyinbo onișowo; ti ẹniti o ti nda paṣẹ ri si tun di ẹniti a npaṣẹ fun? Ti ẹniti awọn enia ti ndahun *yes sir*, *yes sir* fun, ri si tun pada di ẹniti on papa tun nkawọ pọnyin ti o si ndahun *yes sir*, *yes sir* fun oyinbo onișowo miran ti ko to aburo ẹkẹta oluwarẹ papa?

Ni gasikiya, obiri laiye ayida si wa nibi gbogbo. Ti a ba bi ara wa lere ohun ti ima saba fa ayipada bayi wa, esi na ti a le fi koju aidara owo ti o ti nṣe gbogbo araiye bi ọṣẹ ṣ'oju lọ, eyi wa lọna kan.

Lọna keji ẹwẹ orișirișị aniyan to mbẹ fun olukuluku ni ile rẹ, irufẹ aniyan ti o ngbọn owo lo lọwọ pupọ ninu wa bi ẹni ngbọn omi lo si tun nṣe onikọ owo nina gburo bẹ.

Ki a mu apẹrẹ kanṣoṣo ti ẹlomiran nfi gbọn'wo danu nipa ṣiṣe sara ti ko ni gọ-nbọ, wa si iranti wa.

Bi ọfọ ṣeṣi ṣẹ ẹnikan, papa ti ẹniti o ku na ba jẹ arugbo onigbagbọ, lẹhin inawo Ita ati Ije, ni yio wa ṣẹṣẹ kan aṣa ti awọn kan da silẹ, ti nwọn npe ni "*Silling Sunday*" kini njẹ *Silling Sunday*? Ni tiwa itumọ ti a le fun u ni "Ọsẹ Oloraye" ọsẹ ti awọn a-ya'jule jẹun ti nwọn mọ ibi ọbẹ dun da silẹ lati lọ ki ọmọ-oloku yi, ti iyẹn kẹ yio si bẹrẹ si inawo ọti ati ipanu apapa-ndodo lati ṣe fun awọn ti nwọn ko kọ lati sọwọ rẹ dilẹ, ti nwọn si tun mura tan lati bu u le ori gbogbo inawo rẹ bakanna; ofo a-mọmọ ṣe (*Wilful Waste*) ni a mọ inawo *Silling Sunday* si; bẹni eyi ko iti kan inawo ti a o tun ṣe nigbati Ọmọ-oloku na yio ba jade oku lọ si *Church*; ọrọ diẹ ni ọlọgbọn fẹ. A fẹ ki ẹnyin ara wa sapa lati fi opin si aṣa aṣagbe ohun mimu ti awọn kan dasilẹ yi, ti a ko mọ ibiti o gbe wa; oyinbo ko mọ ọ bẹni awọn ara wa igbani ti ọfọ ṣẹ ko mọ; njẹ nibo lo ti wa? Awọn a jẹbọ-kiri kan lo da silẹ; ile olonjẹ la sa ndẹ ẹbiti aiya si! ẹnyin ara, owo ki iṣe ohun kekere lode aiye; bi a ba nmọ ibi ti o wa ninu nina owo si aburadi, bi a ba si gbidanwo lati fi ẹdẹ si laisi aniani, nkan yio ṣe gbẹdẹ fun ẹnikẹni. Ninu ọdun titun yi, adura wa ni pe:—

Ki Baba Onibu Ọrẹ ma ṣai jẹ ki a lowo lọwọ, ki ki a maṣe ni l'ọrun ! ! !

Oṣi ni njẹ tani mọ ọ,
Owo ni njẹ mo ba ọ tan.

TỌWỌBỌLA.

---

## *Stop Press.*

According to the *Daily News* of yesterday, it is said that the Eleko Case has been set down for hearing on or about the 17th April next

---

Iwe-irohin *Daily News* ti ana sọ pe Ẹjọ Eleko yio di riro titi ọjọ 17 oṣu April to mbọ.

---

ABỌ O.

A ki Ọgbẹni E. A. Oluyẹle Bright kabọ Ẹpẹ ati Ijẹbu Ode ti o ti lọ.

---


## FOR SALE.

The Garret House situate at 75, Freeman Street, Ẹpẹtẹdo District, Lagos, to be sold by public auction on Tuesday the 6th March, 1928, at 4 30 p.m. on thespot.

The House situate at 16, Olowu Street, near the Marina, Ẹpẹtẹdo District, to be sold by public auction on Monday the 12th day of March, 1928, at 4.30 p.m. on the spot.

ỌLABOYE LALẸYẸ,
*Licensed Auctioneer.*

"O di ọdun marundi-logoji nisinsinyi ti a ti bẹrẹ si ṣe *Mentholatum*, a si mọ ni kakiri gbogbo aiye bi egbogi ti o wulo fun wiwo:—Otutu orişirişi, Ọna-ọfun ti o ndun-ni, Ori-fifọ, Arun Awọ-ori, ati gbogbo Arun Awọ-ara"

A HEALING CREAM

**Mentholatum**

## SKIN IRRITATION—



**Burns, Cuts, Scalds, Wounds, Bruises, Eczema, etc., are quickly cured by Mentholatum—an antiseptic, healing, soothing, pleasant-to-use preparation. It will take the itching out of Skin Diseases instantly.**

**MENTHOLATUM**

is a scientific combination of menthol, camphor, and oils, with other valuable medicinal and germicidal agents, and is absolutely harmless. It has been

**FOR 28 YEARS A HOUSEHOLD REMEDY**

with an extremely wide range of uses. Strongly endorsed by Physicians on account of its unusual effectiveness. Stocked by all the leading Chemists throughout the World.

Prices 1/3 and 2/6. (2/6 size contains three times the quantity of the 1/3).

***SEVEN MILLION** Pots sold last year.*

THE MENTHOLATUM CO.,
329, High Holborn, London, ENGLAND.
*Send us a post card for a Free Sample.*

**MENTHOLATUM**
"FEEL IT HEAL."

Mentholatum has been manufactured for 35 years and is known throughout the world as a medicine of great value for Colds, Sore Throat, Headache, Scalp Troubles and all skin ailments.

***The Mentholatum Company, Ltd, Slough, England***

*Over 16 million jars sold last year.*

## Disinfectant Soap of Unrivalled Quality

Use Magnet Carbolic Soap in your home—it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.

# MAGNET
## Carbolic Soap Tablets




WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## White's Golden Male Tonic

(DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by Victor White, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—Not Obtainable Elsewhere.
"Shake the Bottle."

AREMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ę ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣę ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe' royin.

Price Ten Shillings (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Paintull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by Victor White Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fę bajẹ, ati orişirişi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

Price 10/- Per Bottle.
**Postage 2/6 extra.**

WHITE'S
## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork than he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, Offin Road, Lagos.
Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size. 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.
N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe, awọn ti o nfi iwe ṣişẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy of Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
Victor White, Esq., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".
Price Ten Shillings (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rę mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşę Ewurę pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D, Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.!

**A Trial is Solicited.**

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

# TO LET.

## One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

# *ILE OWO OYINBO*

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko,

—— : o : ——

Ịle-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọm..
ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to k..
si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi a..
awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si f..
ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.